# DÍDÁ AYÉ

## Gẹnẹsisi 1:1-25

## ẸKỌ 1 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Li atetekọṣe Ọlọrun dá ọrun on aiyé" (Gẹnẹsisi 1:1).**

### Atetekọṣe

Ọlọrun ti wà ni Ọrun Rẹ̀ lati ayebaye, awọn ogun Ọrun n kọrin titi lae yiká itẹ Rẹ̀, wọn n sin In, wọn si n juba Rẹ̀. Ṣugbọn Ọlọrun ninu ifẹ Rẹ̀ ailopin, n fẹ eniyan mimọ́ ti Oun le rọ ojo ifẹ́ Rẹ̀ le lori.

Ni akọkọ O kọ́ gbọdọ dá ayé fun eniyan lati gbé. "Li atetekọṣe, Ọlọrun dá ọrun on aiye." Ko si ohunkohun ninu eyi ti a le fi dá aye. Ọlọrun sọrọ, o si ri bẹẹ. Awọn Onimọ-ijinlẹ ti fun wa ni ọpọlọpọ èrò ori wọn ti wọn rò nipa bi a ṣe da aye, ṣugbọn diẹ ni èrò wọn fi sàn ju èrò ti awọn keferi ọlọgbọn ori, ti wọn sọ ninu iròkurò wọn pe lati inu ẹyin kan ṣá ni ayé ti jade wá. Wọn ko sọ ibi ti ẹyin naa ti jade wa. O ti le ri aworan ọkunrin kan ti a n pe ni Atlas pẹlu ayé ni ejika rẹ̀. Awọn ẹlomiran gbagbọ́ pe omiran nla kan wà ti o gbé ayé le ejika rẹ̀. A rò pe iru ero bẹẹ jẹ ero omugọ, ṣugbọn ohunkohun ti o ba ti lodi si Ọrọ Ọlọrun jẹ ti omugọ. "Aṣiwere wi li ọkàn rẹ pe, Ọlọrun kò si" (Orin Dafidi 14:1). Kò ti i si ẹni ti o fi idi rẹ̀ mulẹ, bẹẹ ni ki yoo si ẹni kan ti yoo le fi idi rẹ̀ mulẹ pe a dá ayé ni ọna miiran yatọ si ọna ti Bibeli fi kọ́ wa.

Kiyesi ọla-nla ti o wà ninu awọn ọ̀rọ̀ ti a sọ wẹ́rẹ́ yii: "Li atetekọṣe Ọlọrun dá ọrun on aiye." Wo iru Ọlọrun Alagbara ti a ní lati sin! Bi o tilẹ jẹ pe o dabi ohun ti o ṣoro lati gbagbọ́ pe a dá ayé lati inu ohun ti kò si, awa ti a jẹ́ Kristiani gbagbọ bẹẹ, a si jẹ́ alabukun fun nitori a gbagbọ́. "Nipa igbagbọ́ li a mọ̀ pe a ti da aiye nipa ọ̀rọ Ọlọrun; nitorina ki iṣe ohun ti o hàn li a fi dá ohun ti a nri" (Heberu 11:3). Awa ti a mọ Ọlọrun ti a si gba A gbọ́ jẹ ẹni ti o layọ. Ayé nipa gbogbo ohun ti o n fi eke pè ni ọgbọn kò ti i ri Ọlọrun sibẹ.

Ṣaaju ohun gbogbo, Ọlọrun sọrọ, awọn ọrun on ayé si wà, ti o dabi iṣù kan ṣaa ti o si fara sin ninu okunkun. Nigba naa ni O bẹrẹsi i mú awọn nnkan ti o ti wà ni júújúú wa si eto. Pẹlu ironu ti o jinlẹ ni O ṣe gbogbo eyi fun iwọ ati fun emi.

### Ọjọ Kin-in-ni

Ni ọjọ kin-in-ni, Ọlọrun dá imọlẹ. Ko si oòrun, oṣupa, tabi irawọ, ṣugbọn Ọlọrun le ṣe imọlẹ lai si wọn, nitori imọlẹ ni Oun. Jesu wi pe, "Emi ni imọlẹ aiye" (Johannu 8:12). "Imọlẹ otitọ mbẹ ti ntàn mọlẹ fun olúkulùku enia ti o wá si aiye" (Johannu 1:9).

Ni oniruuru igba ati akoko ni imọlẹ ti jẹ́ apẹẹrẹ ireti. Awọn wolii ti wọn sọ asọtẹlẹ wiwá Jesu sọ pe yoo dabi imọlẹ ọjọ titun. "Ṣugbọn Õrùn ododo yio là, ti on ti imularada ni iyẹ́-apá rẹ̀, fun ẹnyin ti o bẹ̀ru orukọ mi" (Malaki 4:2). A maa n ṣe apejuwe igbala kuro ninu ẹ̀ṣẹ gẹgẹ bi kikuro ninu okunkun bọ́ sinu imọlẹ: "Ẹnyin ni iran ti a yàn, olu-alufa, orilẹ-ède mimọ́, enia ọ̀tọ; ki ẹnyin ki o le fi ọla nla ẹniti o pè nyin jade kuro ninu òkunkun sinu imọlẹ iyanu rẹ̀ hàn" (1 Peteru 2:9). "Nitorina bi ẹnikẹni ba wà ninu Kristi, o di ẹda titun" (2 Kọrinti 5:17). O ti di ẹda titun ti Ọlọrun, eyi si ṣe pataki fun Un ju didá ayé lọ.

Ọlọrun ri i pe imọlẹ naa dara. Bawo ni imọlẹ ti ṣe pataki to! Awọn nnkan ti o le dagba lai si imọlẹ kò wọ́pọ̀. Ọlọrun, ninu ifẹ Rẹ̀ nla ti fun wa ni imọlẹ fun ara lile ati ayọ̀ wa.

Ọlọrun si paala laaarin imọlẹ ati okunkun, O pe imọlẹ ni Ọsán, ati okunkun ni Òru. "Ati aṣalẹ ati owurọ̀ o di ọjọ́ kini." Eyi ni wakati mẹrinlelogun gẹgẹ bi awọn ọjọ ti wa.

### Ọjọ Keji ati Ọjọ Kẹta

Ni ọjọ keji, Ọlọrun dá ọrun, awọsanma daradara ti a n ri loke, ti o ya omi ti o wà lori ilẹ kuro lara omi ti o wà loke ayé. Omi bo gbogbo ayé, nitori naa ni ọjọ kẹta, Ọlọrun kó omi yii jọ pọ̀ gẹgẹ bi awọn adagun omi, ti a n pe ni awọn okun nla, ilẹ gbigbẹ si fara hàn. Okun Pacific, ti o jẹ akopọ omi ti o si tobi ju lọ, to ẹẹdẹgbaarin (7,000) milè ni ibú, sibẹ omi inu rẹ̀ ko kọja awọn bèbè rẹ̀. Ibi pupọ ni awọn eti okun yí dọgba, ti kò si ohunkohun lati dá omi naa duro, bi ko ṣe ààlà ti Ọlọrun fi sibẹ ti O si wi pe: "Nihinyi ni iwọ o dé, ki o má si rekọja, nihinyi si ni igberaga riru omi rẹ yio duro mọ" (Jobu 38:11). Nitori naa, lati ọpọlọpọ ẹgbẹrun ọdun ti Ọlọrun ti dá okun ni igbi rẹ̀ ti n bi lu eti okun kan naa. Bi a ba dá ayé si ọna mẹta, ọna meji ninu mẹta yii ni omi, ida kan pere ti o kù silẹ ni o si jẹ́ ilẹ gbigbẹ. Awọn ọjọgbọn sọ fun wa pe bi o ti yẹ ki o ri gan an niyẹn lati mu ki nnkan wà laaye ki afẹfẹ pupọ si le fun ni ni ilera. Ọlọrun da a ni ọna bẹẹ, O si ri i pe o dara.

Nisisiyii, ilẹ gbigbẹ wà, Ọlọrun si ni ibi ti yoo gbin igi, itanna ati ewebẹ fun ounjẹ si. Ki i ṣe pe Ọlọrun yoo ṣẹṣẹ ro ilẹ, ki o gbin ohun ọgbin ki o si duro fun wọn lati dagba. O kàn sọ pe, "Ki ilẹ ki o hù oko, eweko ti yio ma so eso, ati igi eleso ti yio ma so eso ni irú tirẹ̀, ti o ni irugbin ninu lori ilẹ: o si ri bẹ̃" (Gẹnẹsisi 1:11). Nigba ti Ọlọrun sọrọ, ti igi si wà, iye wa ninu wọn ki wọn ba le maa mú irú wọn jade funra wọn. Titi di oni oloni ni a ṣi n jẹ awọn eso bi ọsàn, ibẹpẹ, orombo ati awọn ewebẹ bi i gbure, ẹfọ tẹtẹ ati ewedu ati ọpọlọpọ eso ati ewebẹ miiran ti wọn jade wá lati inu awọn ohun ọgbin kin-in-ni wọnni ti Ọlọrun sọrọ, ti wọn si wà bẹẹ. Ọlọrun wi pe olukuluku yoo maa so eso ni iru ti rẹ̀.

Ọlọrun wo gbogbo awọn ohun ọgbin ati igi daradara ti wọn bo ilẹ nisisiyii, ti O ti dá fun eniyan, O si ri i pe o dara,

Ni igba miiran ti o ba n gbadun ẹgusi olomi ti o dùn tabi awo ti o kun fun orombo didùn tabi oriṣiriṣi eso didun ati ewebẹ miiran ki o mọ̀ pe Ọlọrun dà a fun igbadùn rẹ gan an ni. Oun mọ̀ pe ni ọjọ kan, a o bi ọ si ayé, Oun si n fẹ ki o jẹ igbadun awọn ohun ti O ti dá fun ọ.

**A n Sọrọ Ogo Ọlọrun ninu Awọn Ọrun**

Ni ọjọ kẹrin, Ọlọrun dá oorun, oṣupa ati ọpọlọpọ irawọ lati jẹ́ imọlẹ. Oorun ni yoo ṣe akoso ọsan, oṣupa ati irawọ ni yoo si maa ṣe akoso oru. Wo iru agbara ati ayọ ti a n ri ninu itanṣan imọlẹ oorun; ẹwa oṣupa ati irawọ loru ti dara to! Dafidi Onipsalmu kọrin pe, "Awọn ọrun nsọ̀rọ ogo Ọlorun; ati ofurufu nfi iṣẹ ọwọ rẹ̀ han" (Orin Dafidi 19:1). Jobu sọ fun wa pe awọn irawọ jumọ kọrin nigba didá ayé.

Oorun ati oṣupa wà fun ami ati akoko. Alafo ti o wà laaarin ayé ati oorun ati yiyi ti ayé n yi lori ijoko rẹ̀, ni a fi n mọ igba ẹ̀rùn ati òjò. Ni ihà ariwa ayé, a maa n ni igba ẹẹrun ninu oṣu kẹfa, oṣu keje ati oṣu kẹjọ ọdun (June, July, ati August). Ni iha guusu ayé, akoko otutu ni awọn oṣu wọnni jẹ́. Ni tosi agbedemeji ayé, bi nnkan ṣe n gbona si tabi tutu si wà bakan naa yipo ọdun. Ọlọrun wi pe: "Niwọ̀n ìgba ti aiye yio wà, ìgba irugbìn, ati ìgba ikore, ìgba otutu ati oru; ìgba ẹ̃run on òjo, ati ọsán ati oru, ki yio dẹkun" (Gẹnẹsisi 8:22).

**A dá Ẹranko Ẹlẹmi**

Nisisiyii a ti pese ayé silẹ fun awọn eniyan lati gbé. Ọlọrun bẹrẹ lati ọdọ awọn ohun ẹlẹmi ti o rẹlẹ, O dá ẹja ati awọn ẹyẹ. Ọlọrun dá awọn ẹranko keekeekee inu omi, ẹja ati erinmi nla lati maa gbé inu omi. Ninu awọn okun nla, oriṣiriṣi awọn ẹja ti a ko ri ri ni o wà nibẹ, ṣugbọn ọpọlọpọ wọn ni a n lò fun ounjẹ. Ọlọrun dá awọn ẹyẹ lati maa gbé lori ilẹ, ati lati maa fò ni ofuurufu, ẹran ara wọn si yatọ. "Gbogbo ẹran-ara ki iṣe ẹran-ara kanna: ṣugbọn ọ̀tọ li ẹran-ara ti enia, ọ̀tọ li ẹran-ara ti ẹranko, ọ̀tọ ni ti ẹja, ọ̀tọ si ni ti ẹiyẹ" (1 Kọrinti 15:39). Ọlọrun dá ọkọọkan wọn ni iru ti rẹ̀, ko si si iyipada lati iru kan si ekeji. Oriṣiriṣi ẹṣin, ibaaka ati kẹtẹkẹtẹ ni o wà, ṣugbọn ko ti i si ẹṣin ti o yipada si maluu ri, bẹẹ ni aja ko ti i yi pada di ẹṣin ri. Awọn ẹlẹkọọ nipa ohun ẹlẹmi ti gbe ọpọlọpọ ero ori wọn kalẹ pe eniyan ti inu legbenlegbe tabi ọbọ jade, ṣugbọn ko si ẹni ti o ti i le fi hàn pe eniyan ti jẹ ohun kan tẹlẹ bi ko ṣe eniyan, ki a ma ṣẹṣẹ sọ ti legbenlegbe. Ọlọrun dá gbogbo ẹranko, gbogbo ẹja ati ẹyẹ, olukuluku si wa ni iru ti rẹ̀ titi di oni-oloni.

Nigba ti Ọlọrun ti dá gbogbo oniruuru ẹyẹ ati ẹja ti o lẹwa ti o si wu ni, O ri i pe o dara. O sọ fun wọn pe ki wọn maa bi si i, ki ọpọlọpọ wọn le wà yika gbogbo ayé. Bayii ni ọjọ karun-un pari.

**Ọjọ Kẹfa**

Ni ọjọ kẹfa, Ọlọrun wi pe: "Ki ilẹ ki o mu ẹdá alãye ni irú rẹ̀ jade wá, ẹran-ọ̀sin ati ohun ti nrakò, ati ẹranko ilẹ ni irú rẹ̀," o si ri bẹẹ. Ọpọlọpọ ohun iyanu nipa dida aye ni o wà ninu kòkòrò keekeekee, gẹgẹ bi o ti wà ninu awọn ẹranko beari ati erin ti o tobi.

Lati inu ilẹ ni Ọlọrun ti dá awọn ẹranko akọkọ wọnyii, ṣugbọn wọn n bi si i ni irú ti wọn, a ko si mu wọn wá lati inu ilẹ mọ́.

Wo bi ayé ti ni ẹwa to titi di isisiyii. Loroowurọ ni oòrùn n yọ lati ràn sori pápá ati pẹtẹlẹ. Awọn ẹranko n jẹ koriko pẹlu alaafia ninu igbo ati ni pápá oko tutu, nigba ti awọn ẹyẹ n kọrin bi wọn ti n fò loke. Awọn odo ti ẹja kun inu wọn pupọ n ṣàn pẹlu ayọ lọ sinu okun. Awọn erinmi nla inu okun ati awọn ẹja keekeekee n ṣire pọ̀ ninu ibu okun nlá. Alaafia Ọlọrun si n ṣe akoso lori gbogbo wọn. Gbogbo eyi ni Ọlọrun ti ṣe gẹgẹ bi ibugbe fun olubori ẹda ọwọ rẹ -- eniyan. Eyi ni ohun ti eniyan kin-in-ni, Adamu, ri nigba ti o kọ la oju ri imọlẹ ayé.

**AWỌN IBEERE**

1 Bawo ni ayé ṣe wà? Bawo ni a ṣe mọ̀?
2 Ki ni Ọlọrun ṣe ni ọjọ kin-in-ni?
3 Ki ni Ọlọrun sọ ni opin iṣẹ ọjọ kọọkan ni igba didá ayé?
4 Ki ni ṣe ti Ọlọrun dá ayé?
5 Ki ni ṣe ti okun duro si àyè rẹ̀?
6 Orişirişi ẹran-ara wo ni o wà?